Ìrìbọmi Ló Máa Fìdí Àjọṣe Rẹ Pẹ̀lú Ọlọ́run Múlẹ̀ (Apá 2)

A gbé e ka orí 18 nínú ìwé *Kí Ni Bíbélì Fi Kọni Gan-an?* ó wà lórí ìkànnì www.jw.org/yo.

OHUN TÍ O FẸ́ ṢE: Ṣàyẹ̀wò ohun tó o gbà gbọ́ àti ìdí tó o fi gbà á gbọ́, wo ohun tí Bíbélì fi kọni, kó o sì mọ bí wàá ṣe ṣàlàyé àwọn ohun tí o gbà gbọ́ fún àwọn ẹlòmíì.

KÍ LÓ MÁA FI HÀN PÉ ỌMỌ ẸNÌ KAN TÓÓTUN LÁTI ṢE ÌRÌBỌMI?

1 ṢÀYẸ̀WÒ OHUN TÓ O GBÀ GBỌ́

Kí làwọn kan lè sọ?

Kí ni **ìwọ** rò nípa rẹ̀?

Kí nìdí tó o fi gbà bẹẹ̀?

www.jw.org © 2017 Watch Tower Bible and Tract Society of Pennsylvania

2 WO OHUN TÍ BÍBÉLÌ FI KỌ́NI

Kí Kristẹni kan tó lè ṣèrìbọmi, ó gbọ́dọ̀ máa ṣe ohun tó ń múnú Ọlọ́run dùn.

(Wo orí 18 nínú ìwé *Bíbélì Fi Kọ́ni*, ìpínrọ̀ 8 sí 13.)

Ka Jeremáyà 20:9; 2 Kọ́ríńtì 4:13.

Kí ló yẹ kí ìgbàgbọ́ tí Kristẹni kan ní sún un ṣe?

Ka Ìṣe 3:19.

Kí Kristẹni kan tó ya ara rẹ̀ sí mímọ́ fún Ọlọ́run, àwọn nǹkan wo ló gbọ́dọ̀ kọ́kọ́ ṣe?



Tó o bá fi mọ́tò kan ṣe ẹ̀bùn fún ọ̀rẹ́ ẹ, ìwọ kọ́ lo máa di kọ́kọ́rọ́ mọ́tò náà mú, o ò sì ní sọ pé dandan, ìwọ ni wàá máa wà á. Lọ́nà kan náà, tó o bá ti ya ara ẹ sí mímọ́ fún Jèhófà, tàbí tó o fi ara ẹ fún un, ṣe lò ń sọ pé ìwọ kọ́ lo ni ara ẹ mọ́, òun ni kó máa darí ẹ

www.jw.org © 2017 Watch Tower Bible and Tract Society of Pennsylvania

Kí Kristẹni kan tó ṣèrìbọmi, ó gbọ́dọ̀ kọ́kọ́ ya ara rẹ̀ sí mímọ́ fún Ọlọ́run lóun nìkan.

(Wo orí 18 nínú ìwé *Bíbélì Fi Kọ́ni,* ìpínrọ̀ 14 sí 16.)

Ka Diutarónómì 6:15; Máàkù 8:34.

Kí ló túmọ̀ sí kí ẹnì kan ya ara rẹ̀ sí mímọ́?

Ka 1 Pétérù 4:2.

Kí ni ìyàsímímọ́ ní ín ṣe pẹ̀lú ohun tó máa ń wu Kristẹni kan àtàwọn ohun tó fẹ́?

Àwọn àtúnṣe wo lo ti ṣe nínú ayé ẹ báyìí kí inú Ọlọ́run lè dùn sí ẹ, àwọn àtúnṣe míì wo ló ṣì máa wù ẹ́ kó o ṣe?

www.jw.org © 2017 Watch Tower Bible and Tract Society of Pennsylvania

3 ṢÀLÀYÉ ÀWỌN OHUN TÍ O GBÀ GBỌ́

TÍ ẸNÌ KAN BÁ SỌ PÉ…

Kì í ṣe dandan pé káwọn Kristẹni máa wàásù. Ohun tí Ọlọ́run fẹ́ ò ju pé, ká ṣáà máa ṣe dáadáa.

O LÈ SỌ PÉ…

Ó ṣeé ṣe ṣe kí àwọn kan gbà pẹ̀lú ohun tẹ́ ẹ ṣọ yẹn. Àmọ́ èmi gbà pé ojúṣe mi ni láti wàásù torí pé…

_____

_____

Ẹṣẹ Ìwé Mímọ́ wo lo máa kà fún ẹni náà?

_____

Pẹ̀lú ohun tí ẹni náà gbà gbọ́ yìí, báwo lo ṣe máa ṣàlàyé ẹṣẹ Ìwé Mímọ́ náà fún un?

_____

TÍ ẸNÌ KAN BÁ SỌ PÉ…

Báwo lèèyàn ṣe máa ṣọ pé gbogbo ayé òun lòun fẹ́ fi fún Ọlọ́run, láì kì í ṣe agbawèrèmẹ́sìn?

O LÈ SỌ PÉ…

Mo gbà pé òótọ́ ni pé Ọlọ́run ò fẹ́ ká gba wèrè mọ́ ẹ̀sìn. Síbẹ̀, mo gbà pé gbogbo ọkàn mi ló *yẹ* kí n fi sìn ín torí pé…

_____

_____

Ẹṣẹ Ìwé Mímọ́ wo lo máa kà fún ẹni náà?

_____

Pẹ̀lú ohun tí ẹni náà gbà gbọ́ yìí, báwo lo ṣe máa ṣàlàyé ẹṣẹ Ìwé Mímọ́ náà fún un?

_____

www.jw.org © 2017 Watch Tower Bible and Tract Society of Pennsylvania